

# Josemaria Escriva Mímọ́

## Olùdásílẹ̀ Opus Dei

## ÀDÚRÀ

*Ọlọ́run, nípaṣẹ̀ Màríà Wúńdíá alábùkúnfún, ìwọ fi ọ̀pọ̀ oore-ọ̀fẹ́ fún àlùfáà rẹ, Josemaria Mímọ́ nípa yíyàn gẹ́gẹ́ bí irinṣẹ́ olódodo jùlọ̀ láti dá Opus Dei (Iṣẹ́ Ọlọ́run) sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìsọ-ara-ẹni-di-mímọ́ lẹ́nu iṣẹ́ òòjọ́ wa, nínú àṣeyọrí iṣẹ́ ìsìn wa gẹ́gẹ́ bí onígbàgbọ́. Fífún mi pé kí emi náà lè kọ́ láti sọ gbogbo ìgbésí àti ìṣẹ̀lè ayé mi di àwọn ohun àǹfààní láti fẹ́ràn rẹ àti láti sin ìjọ Eklesia, Pápà Mímọ́ àti gbogbo ènìyàn pẹ̀lú ayọ̀ àti ìrẹ̀lẹ̀ ọkàn nípa fífi ìgbàgbọ́ àti ìfẹ́ tan ìmọ́lẹ̀ sí ọ̀nà ayé yìí.*
*Jọ́wọ́, nípa ẹ̀bẹ̀ ìránṣẹ́ rẹ, Josemaria Mímọ́, gbọ́ ẹ̀bẹ̀ mi yìí... (níbí, sọ ẹ̀dùn ọkàn rẹ) Àmín.*

Bàbá wa tí n bẹ lọ́run, Mo kí Ọ Màrià, Ògo ni fún Bàbá.

*"Ibikíbi tí ìlàkàkà yín, iṣé yìn àti ìfẹ́ yín bá wà, ibẹ̀ gan-an ni ẹ ó tí ṣe àbápàdé Kristi lójoojúmọ́. Ibẹ̀ náà si ni, láàrin àwọn ohun ara ti ayé yìí ni a gbọ́dọ̀ ti ya ara wa sí mímọ́ bí a ṣe ń sin Ọlọ́run àti gbogbo ènìyàn.*

*Ó dàbí ẹni pé ọ̀run àti ayé ń papọ̀ ní sánmọ̀, ẹ̀yin ọmọ mi. Ṣùgbọ́n ibi tí wọ́n ti ń pàdé gan-an ni ọkan yín, nígbà tí ẹ bá ń ya ara yín sí mímọ́ lójoojúmọ́ láti ara iṣẹ́ òòjọ́ yín..."*

*– Ìwàásù Josemaria Escriva Mímọ́ lórí àkòrí: "Fífẹ́ràn ayé nípa ìkáàánú tòótọ́" tó ṣe ní October 8, 1967.*

A bí Josemaria Escriva Mímọ́ ní ìlú Barbastro, Ilẹ̀ Spain, ní ọjọ́ kẹ́sàn-án, oṣù kínní, ọdún 1902. Ó gboyè àlùfáà ní ọjọ́ Kejìdínlọ́gbọ̀n, oṣù kẹta ọdún 1925, ní ìlú Saragosa. Ó da Opus Dei (Iṣẹ́ Ọlọ́run) sílẹ̀ ní ọjọ keјì, oṣù kẹwàá ọdun 1928 ní ìlú Madrid nípa àgbéǹde ìmísí Ọlọ́run. Ní ọjọ́ kẹrindínlọ́gbọ̀n oṣù kẹfà ọdún 1975 ni ó jé ìpè Ọlọ́run láìròtẹ́lẹ̀ nínú iyàra ibi tí ó tí máà ń ṣiṣẹ́ ní ìlu Róòmù lẹyìn tí ó fi tifẹ́tifẹ́ wo àwòrán Màríà, ìyá wa. Lákòókò ikú rẹ̀ yìí, ẹgbẹ́ Opus Dei ti tàn ká orílẹ̀ máarùn-ún tí aye pin sí, tí àwọn ọmọ ẹgbẹ́ sì, ti lè ní ọ̀kẹ́ mẹ́ta ènìyàn, ní àwọn orílẹ̀-èdè bi i ọgorin. Àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Opus Dei ń ṣíṣẹ́ Eklesia pẹ̀lú ẹ̀mí ìsọ̀kan pipe kan náà pẹ̀lú Pàpá Mímọ́ àti àwọn Bísọ́ọ̀bù gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ Josemaria Mímọ́. Pápà Mimọ́, Jòháánù Pọ̀ọ̀lù keјì gba Olùdásílẹ̀ Opus Dei, Josemaria Escriva Mímọ́, gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára àwọn ẹni mímọ́ ní ọjọ́ kẹ́fà oṣu kẹwàá ọdún 2002. A maá ń ṣe àjọ̀dún rẹ̀ ní ọjọ́ kẹrindínlọ́gbọ̀n oṣu kẹfà. Ará Josemaria Mímọ́ ń sinmi ní ile ìjọsin Prelatic tí ìyá wa Àlàáfíà, tí ó wà ní viale Bruno Buozzi, 75, ní ìlú Ròòmù.

A lè bèèrè fún ohunkóhun tí a fẹ́ mọ̀ sí i nípa Josemaria Escriva Mímọ́ ní: www.opusdei.org; www.josemariaescriva.info.

Kí àwọn tí o bá rí ìrànlọ́wọ́ gbà nípa ẹ̀bẹ̀ Josemaria Escriva mímọ́ fi to Alábòójútó/Olùdarí Opus Dei ni 35 Adeola Hopewell Street, P.O. Box 72484, Victoria Island, Lagos. E-mail: ocs@opusdei.org.ng